# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No 761 WEDNESSDAY AUGUST 5 1964 (2D)


## Fani - Kayode Padanu Ipo Igbakeji Olori Ẹgbẹ Dẹmọ

IBADA :- Ni Ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi ni Irohin ti de ọwọ lati Ibadan pe awọn Ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ NNDP ti pa ipo igbakeji Olori ẹgbẹ wọn rẹ eyiti Oloye Rẹmi Fani - Kayọde ti wa tẹlẹ ri.

Awọn Ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ pa ipo na rẹ nigbati awọnn nṣe eto ofin ẹgbẹ na nibi Ipade kan ti nwọnṣeni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹta Oṣu yi ni nwọn ẹgbẹ na ti ṣe aṣaro lati yọ ipo Igbakeji Olori Ẹgbẹ na kuro ninu eto ofin Dẹmọ

Gẹgẹbi eto Ofin ẹgbẹ na ti nwọn ṣeṣẹ bayi ni Oloye S. L. Akintọla ti wa gẹgẹbi Baba Isalẹ ẹgbẹ Dẹmọ ti Ọgbẹni R. O. A. Akinjide si wa gẹgẹbi, akọwe agba ẹgbẹ na. Irohin fi ye pe iru ipo ti nwọn yio fi Oloye Rẹmi Fani-Kayọde ninu ẹgbẹ na ni awọn ẹgbẹ na ko si mọ gẹgẹbi nwọn yio ṣe ṣe yio ti Fani-Kayọde si

Oniwe Irohin wa fi ye wa pe nigbati awọn oniwe Irohin lọ ba Ọgbẹni Akinjide lati sọ iru ipo ti nwọn yio fun Oloye - Fani Kayọde ati ohun to fa ti nwọn fi pa ipo igbakeji Olori ẹgbẹ wọn rẹ? Ọgbẹni Akinjide fi ye awọn Oniwe Irohin pe ki nwọn fi ọrọ na silẹgẹgẹbi awọn ẹgbẹ ṣeṣe ipo ẹgbẹ na si.

## Okotie-Eboh Ha Fẹ Di Ọmọ Ẹgbẹ Olomi Bi?

# OKOTIE-EBOH LỌ BA SARDAUNA Ṣ'ỌRỌ ASIRI

KADUNA:— Alakoṣo eto Isura fun Ijọba apapọ ilẹ Naijiria Oloye Festus Okotie Eboh yara sare lọ si Kaduna ni Ipinlẹ Ariwa Naijiria ni ọjọ Aje ti se ọjọ kẹta su fun ọrọ asiri on pẹlu Alakoṣo Ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria ati olori ẹgbẹ Olomi Alhaji Ahmadu Bello Sadauna ilu Ṣokoto



Ọlọla Ahmadu Bello

Irohin fi ye wa pe Oloye Festus Okotie-Eboh ati ọmọbinrin akọwe rẹ kan pẹlu Ọlopa to ba nrin lọ pẹlu rẹ wọ inu ọkọ ofurufu ni ibudo ọkọ ofurufu ni Ikẹja ni dede agogo mọkanla owurọ ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi lati ya ra lọ si Ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria.

Irohin tun fi ye wa pe Oloye Festus Okotie Ebo yara sọ kalẹ ninu ọkọ ofurufu eyiti Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria ma a nlo ati po lẹsẹkẹsẹ na ni o ya ra lọ si ile kan ni ibudo ọkọ ofurufu ti ilu Kaduna lati duro de mọto ayọkẹlẹ kan ti Ijọba Ipinlẹ Ariwa ti yio gbe lọ si ile Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria ni Nasarawa nibiti Oloye Okotie-Eboh yio ti sọrọ aṣiri pẹlu Ọlọla Alhaji Ahmadu Bello Sardauna ti ilu Sokoto,

Oniwe Irohin ni Kaduna tun fi yewa pe lẹsẹkẹsẹ ti Oloye Festus Okotie - Eboh ti de na ni Mọto Ayọkẹlẹ na ti gbe lọ si Ile Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa Ọlọla Alhaji Ahmadu Bello ni Nassarawa nibi ti Oloye Okotie - Eboh ti ba Olori Ẹgbe Olomi N. P, C. ati Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa Naigiria Alhaji Ahmadu Bello sọro fun odindi Wakati kan. Oniwe Irohin wa tun sọ ninu Irohin rẹ pe ọpọlọpọ awọn Alakoso ti Ijọba Ipinlẹ Ariwa lọ wa nibi Ipade ati awọn enia Jankanjankan ninu awọn ọmọ Ẹgbẹ Olomi N, P. C to wa sibi ipade na, Eyi ni ninu awọn ẹnia to wa sibi Ipade ti Oloye okotie – Ebo ba awọn enia na ṣe awọn ni, Alakoso eto Iṣuna ti Ijọba Ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria Alhaji Aliyu Makaman Bida, Alako so eto Eko ni Ipinlẹ Ariwa Alhaji Isakoita, Alakoso eto ilẹ Alhaji Musa Gashash ati Alakọso eto Ọgbin ti Ijọba Ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria ati Akowe agba ẹgbẹ Olomi N. P C. Alhaji Ahman Galadiman Pategi,

Lẹhin ti nwọn ṣe ipade na tan ni Oloye Festus Okotie-Eboh ba a w ọ n Alako—so Ijọba Ipinlẹ Ariwa wọ mọto ti nwọn si mọto wọn wọde lati lọ ba Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria Alhaji Ahmadu Bello lọ si ibudo ọkọ ofurufu lati lọ da gbere fun un.

Irohin tun fi ye we pe Alakoso ipinle Ariwa ile Naijiria si ba ọkọ ofurufu lọ si Sokoto gegebi irohin lati ile iṣe irohin ti Ijọba ipinle Ariwa Naijiria fi ye wa pe Alhaji Ahmadu Bello yio ba ọkọ ofurufu lọ si Jerusalum ni ọjọ Ru ti iṣe ọjọ kejila oṣu yi lati lọ j ipe kan ti Ijọba ile Jordan pe Ọlọla Alhaji Ahmadu Bello Irohin na tun fi ye wa pe Alhaji Amadu Bello tun ba ọkọ ofurufu padi si ilu Kaduna ni ọjọ Aiku ti iṣe ojo kerin osu yi.

Irohin lati ọwọ oniwe irohin wa ni Kaduna fi ye wa pe lehin ti oloye Festus Okotie Eboh de ibudo oko ofurufu tiKaduna awọn ẹgbẹ olomi N, P, C, tun ba Oloye Okotie Eboh se ipade kan ni ile itura ti ibudo o o ofurufu na lati jinroro lore,

awọn ọrọ kan to tun jẹ asiri Oniwe Irohin wa tun fi ye wa pe Oloye Festus Okotiẹ Eboh ati awọn Alakoṣo Ipinlẹ Ariwa se Adehun lori ọrọ kan to jẹmọ ọrọ Oṣelu Irohin tun fi ye wa pe ibiti wọn tise ipade na pe Alakoṣo Ipinlẹ Ariwa Ilẹ Naijiria Alhaji Ahmadu Bello ko si nibi ipade na rara

Iwe Aṣẹ II

Oniwo Irohin tun fi ye wa pe lẹhin ti wọn pari ipade pe Alakoṣo to iṣura ipinlẹ Ariwa Alhaji Aliyu si gbe iwe kan lọwọ eyiti ojẹ pe inu rẹ ni iwe adehun ti wọn ṣe wa.



Oloye Okotie—Eboh

Nigbati oloye Okotie-Eboh pari ipade na tan pẹlu awọn Alakoso ipinlẹ Ariwa lo yara sare lọ ba Alakoso ipinle Ariwa ile Naijiria nibi ti ọkọ ofurufu ti yio mọ lọ si Ṣokoto ati Alakoso eto isuna ti nwọn si tun ba ọlọla Alhaji Ahmadu Bello tun sẹ asaro kan titi ọkọ ofururu ti yio gbe Alhaji Ahmadu Bello lọ fi kuro ni ibudo ọkọ na.

OJU EWE KẸFA

# AYUNỌRUNBỌ ATI PANPALASO (Apa Karun)

LATI ỌWỌ:— **J. O Shoyinka**

## AYUNỌRUNBỌ PARADA ODI OSUMARE

Osumare ta, o kan ilẹ, kan oke, Ayunọrunbọ wa ni agbede meji, ori rẹ nikan ni nwọn ori nwọn ko ri apa nwọn ko ri ẹsẹ. Ẹru ba wọn gidigidi, nwọn ko le siu wo o, ni ori oju rẹ pọn bi ẹrẹ ẹyin, o ni "ẹnyin enia mi ẹ ku arẹ, ẹ ku wahala A b a n i k u ọrẹ ko si, bi ẹ ti sọ pe dandan ndan ẹ o ba mi de ojule mi nko kọ ayan gbẹ aja dun, ki o yangbẹ ni nkan ati de ajule ọrun ki ṣe kekere, iranlọwọ kan ni ngo ṣe fun yin, nko si nyin gẹgẹbi iṣẹ yin.

Mo mọ dajudaju pe iṣe lẹwa dẹja, ẹnit o ba fi idan yio ri dan ni ọrọ nyin nba paṣẹ fun Maleka iku wipe ko ju ida si agbedemeji okun ti ẹ di ọmọ gbogbo nyin ni iba ku rauraru, ṣugbọn niwọn bi ẹ ti fi mi purọ pe emi ni ẹ tele wa si ọrun. Kini kan ki yio ṣe yin, ṣugbọn ati pada wale ni nko le sọ.

Nisisiyi ngo ran awọn ẹiyẹ oluranlọwọ si nyin, ẹ maṣe jafara, ti nwọn ba ti fo de ọdọ nyin ẹ mabẹru, ẹ jawọ lara okun

Ayunọrunbọ ko gbagbe awọn ọrẹ rẹ loto, o ran awọn ẹiyẹ Idi si wọn, awọn ẹiyẹ wọnyi e ni igba (200 Birds) nwọn fi iyẹ ko iyẹ, iriri wọn dabi ẹnipe ma'eka kan tẹ ẹni soju ọrun, awọn ọmọ eriwo jawọ kuro lara okun nwọn wọ wọrọwọrọ bi Odu agbọn sẹhin awọn ẹiyẹ wọnyi ọrọ na di agbefo, awon ẹiye wọnyi ngbe wọn lọ fẹ ẹ, fẹ ẹ, fẹ ẹ, ti ti nwọn fi so wọn kalẹ ni Bode Alakeji ilu IKU.

Akọle ti "wọn ko si ẹnu ọna Bode na niyi:-Eyi ni Bode Alakeji Ilu Iku.

Dẹdẹgbo, nigbati nwọn kan irẹwẹsi de bi wọn, nwọn bẹrẹ si ba ara wọn sọ pe, opin de, opin de, ohun ti o buruju ni ilu yi nipe ko si ohun alaye kan nibẹ, gbogbo rẹ si funfun lọ lau, agbara kaka ni atẹgun fi nfẹ nibẹ. Bi nwọn ti nwo ko-oko-o bi igala ti o lu takute, ni Ayọrunbọ yọ si wọn, nigbati nwọn foju kan Ayọrunbọ, inu wọn dun ṣẹnṣẹn.

### AYỌRUNBỌ BẸRẸSI SỌRỌ

Ẹ ku lailai, ẹ ku atijọ, oju to ri nyin ma gbo ke ke bi obi, bawo ni ilu wa yi tiri? mo si ro pe ẹ nfi igbaun ṣayọ nihin? lọrọ kan, o nfi wọn ṣe ẹfẹ, inu nwọn bajẹ gidigidi, nwọn ko le sọrọ. Nisisiyi ara nko ni purọ tan yin jẹ nibi ti ẹ o ti parada,




o bọ ago yin silẹ nihin, alaye kan kole wọ ajule ọrun laikojẹ pe o di oku. Ọkan ninu wọn nbere lọwọ Ayọrunbọ pe, ṣe ọlọjọ de niyẹn? Ayunọrunbọ ni koiti de, ṣugbọn o rsun mọ etile-gbogbo wọn dorikodo, nwọn nronu, nwọn ti ku sara patapata.

### ABURO IKU DẸDẸGBO DE.

Aburo iku lo kọkọ de, o ba wọn nibi ti nwọn ti kari bo u bi ahun, o ki wọn, awọn na si kii, o ni ki.i ẹ wade ihin, nibo ni ẹ si nlọ? nwọn ni ọrẹ wọn Ayunọrunbọ ni awọn ba de ihin yi, sugbọn o fi awọn si ẹ ọ, awọn ko si mọ ibiti o wọ lọ.

Aburo iku rẹrin kekeke, otu ẹrẹkẹ wuya, o rẹrin de Akinyẹmi ara o ni irinajo ti ẹ ba ọrẹ yin wa yi arimọ ni eyi jẹ fun nyin emi ni aburo iku dẹdẹgbo gẹgẹbi ẹyin papa ti ma ndapara ti ile aiye pe nko ni pa ọ ṣugbọn ngo fi aburo iku han ọ emi na niyi ngo fi ara mi han yin ni ẹkun rẹrẹ. Ko ni kun to, ko si dun to ti nko ba ṣe alaye diẹ nipa aburo iku gigun rẹ gato ẹsẹ mẹjọ igba aya rẹ dabi ti Kiniun eti rẹ pamọ lori ori ṣekele ṣekele bi ti egbere oju rẹ darojẹ o wa ri kanta kanta bi ti golugọ apa rẹ kọkan ri bir pa bi itakun igi ose ete rẹ ri bi ti Rakunmi ehin kẹ toṣi li owa li enu re, ọkan na pọn bi eh n Ọya owa dabi ọkọkan esẹ r nipọn ribiti ribiti bi ẹsẹ Erin ni kukuru iduro rẹ ba da lẹru.

Oju oku ṣi wọn lọrun o bẹrẹsi fi wọn lakalaka ori ẹ mọ aburo iku loni abi ẹ ko mọ, nwọn ni awọn mọ

Obẹrẹsi fi nwọn ṣe ẹfẹ, oni ẹkọ itu mọ to nigbati ẹba mọ mi dada tan bi aiye lẹwa ni o bi Ọrun ni o ẹ ki yio le sọ o sa bẹrẹ fi nwọn nfi wọ titi ahọn yọ di lẹnu pe ẹ loju wọn silẹ osi po ora iku ọku rin kukuru wọ ede Gbarẹ ti iku ti wọle de oju nwọn ti yi pada lagba ri gbobgo wọn bẹrẹs ṣe iran nkan ikuliasọ rẹ ju wọn loju gbọn ori wọn si wale nwọn to la Iku ti yra pada odi afẹri iku bẹrẹsi ba nwọn sọrọ sugbọn wọn ko ri.

Oni ẹnyin ọmọ Adamọ ẹda Abirun ko si ọna pe ki ẹ ma dẹja.


**UROLYSN DRAGES'**

Fun Itọju tabi fifọ Apo Ile Itọ (Kidney-Bladder) fun Ọkunrin ati Obinrin bi awọn amodi wọnyi ba nyọ o ti ẹnu. ẹhin didun Ibadi Gige tabi riro, eri ile itọ'a tabi tlọ-jijo enisito rirun, rukuruku sẹ,ọn, aikoleri itọ lati ọ to, lakuregbe, orunkun ọwọ, ẹ. Ejika wiwu tabi rirọ

Ara sisan. titobiju aiko le gbe ara kọnkọn tabi kiakia didaj loru nigbakugba, ati orişirişi awọn aisan tabi amodi, ba wọn. yi ni egbogi ajẹbidan yi yio wo san lara rẹ ni kiakia ti alafia yio si de si ọ. Meji rẹko si ni ilu Naijiria nitorina ṣọra ki awọn eleru tabi awọn ori rọbirọbi ma ta orişi omiran ti ko ni lari fun ọ, maṣe gba rara! Owo rẹ jẹ Sile mẹfa abọ 6/6d owo Ọkọ Sile kan abọ (1/6d)



Bere Egbogi yi ni ọbu awọn:—

NIGERIA MEDICINE STORES
4 TIUNBU SQUARE, LAGOS

# IWE SI OLOTU

## Mo kan Saara si Olotu

Olotu eti awọn alaba ṣiṣẹ pọ rẹ mo si dupẹ pupọ lori idajọ Baba wa Oloye Awol wọ ti ẹ jẹ ki awa Ọmọ ilẹ ẹkọ ti ko ti ile ka iwe lede Oyinbo nri ka ninu we nyin Oleyiomọmọ "Irohin Imọlẹ." Eleyi ṣi ji ko jẹ Ibauujẹ fun ẹdun ọkan mi nigbati a ko le ri i e Irohin ti yio fun wa ni ẹkunrẹrẹ idajọ na lede Yoruba.

Ṣugbọn mi ko mọ gẹgẹbi ọkan mi ti i nigbati mo ri iwe Irohin Imọ le ti ọjọ kẹtala Oṣu keji Ọdun yi ti mo ri ka pe ẹkunrere idajọ na yo jade ni ọjọ kejọ na. Ako si ti ṣọ fuu gbogbo ọrẹ mi ati pe nu awọn Ẹlẹgbẹ mi si dun pupọ nigbati a ri Irohin na ka ni Owurọ ọjọ keji. Gẹgẹbi Olotu iwe Irohin Imọlẹ ti sọ pe aleyi yio jẹ Ohun Itan lotọ ni yio jẹ ohun itan. Mo si dupẹ gidigidi fun iranlọwọ ti Olotu Irohin Imolẹ ṣe fun awa Ọmọ Ile Ẹko ti ko ti la ka iwe Irohin lede Oyinbo ti o jẹ ki asi nri iwe na ka, Inu wa yio dun bi iwe a ba rete nde ilu wa nigba gbogbo,

Emi ni
Ọlatunde Dauda
Odolẹwu Ijẹbu-Ode

Ohun ti o sẹlẹ na nipe gbogb wọn ọmọ Naijiria ko ra wọn jọsi ibi itosi ile ti wọn tise ipade na

nigbati Alakoso Naijiria se si de. Awọn bẹrẹsi pariw le lori ti wọn si nbu pe ki o sare ya fi oloye Awoiow ṣiiẹ Iwa yi ko da ra lati ma bu Alakoso ilẹ wa ni ilu okere Itiju nla ni osi tun jẹ B io tilẹ jẹ pe oluwa ẹfẹ nka tio ba de iwe ni o yẹ ki wou han nipa bi nkan ti nlo si ni i ẹ

Ẹ a sire kowe si Alakoso na fun idarijin nitor ẹli doju ti loju gbogbo aiye

Emi ni
U, S, A. Bisi Adekoya

## Ẹ ma Binu, Sa

OLOTU Inu mi yio dun pupọ ti ẹ ba le gba mi laye diẹ ninu gbajumọ iwe irohin Imọlẹ rẹ Aladun lati bẹ Alakoso Ijọba Apapọ Alhaji Abubakar Tafawa Balẹwa pe ki nwọn jọwọ maṣe binu nipa hiho ti awọn ọmọ Naijiria ho lelori ilu Oyinbo nigbati wọn fi lọ sibi ipade Ẹgbẹ Igbimọ Agbaiye (Commonweath Conference).

Ẹ jọwọ Alagba ẹ maṣe binu Agba ti ko ba binu ni ọmọ rẹ pọ, ẹ jọwọ ẹ dari jin awọn ọmọ Naijiria.

Ẹ seun o ẹ ku iṣẹ o.

Olotu mo dupẹ aye ti ẹ gbami Oluwa ko wa pẹlu yin.

Emi ni
Florence Olarewaju
Middlesex England.

## Ogbogbo Nfẹ Atunse

Olotu jọwọ gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin oleyinmọmọ adura mi si nyin ni pe ki Ọlọrun ma ba nyin gbe ki iwe Irohin Imọlẹ na ni itẹsiwaju

ọrọ mi na ni pe mo kesi Olotu Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Oloye S L Akintọla ki o lo ipo rẹ rere lati kesi Alakoso eto iṣẹ Ijọba Ipinlẹ rẹ lati ba wa mu oju to ilu wa Ogbogbo ni Ijẹbu lati le ba wa ṣe atuuṣe gbogbo ọna ilu na ati awọn nkan miran to yẹ ki Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ṣe fun ilu Ogbogbo nipa eto ilọsiwa ilu na

Inu awa ọmọ ilu Ogbogbo yio dun bi Ijọba Akintọla ba le tete ṣe awọn nkan lwọnyi fun ilu wa nitoripe awọn eaia ilu na ki ifi o [illegible] jafara lati san ati p e asi nfẹ awọn nkan ti yio mu ilọsiwaju ba ilu na ao si ma reti Ijọba nyin o

Mo dupẹ pupọ o Olotu

Emi ni
Ọladele Ogunlẹyẹ IJẸBU

## E fi Awo Sile

Ki ise pe ki a ma paiwo Awolọwọ kiri ni yio gbe jade tabi i a ma lu ilu kiri ki a si ma ki ni o le san lọwọ eyi tun nda si lọrun ni ti a ba mọ pe a ni ifẹ Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ẹ jẹki a kun fun adura atokan wa ki o le gbe jade wa ba wa ni alafia.

Ọpọlọpọ ninu wa ti o kigbe Awo! Awo!! Awo!!! ni ko ai ifẹ rẹ deiwu, ẹ jeki a simi ajwo rẹ ti a pakiri ki a ss sesi a ko tile fẹ mọ ki awi duro de ibo lati fi gbe jade eleyi ni emi ri pe ole ran wa lọwọ.

Nitori odi ọwọ wao,
Lati Ọwọ,
FATAYI OYERGBA.

## Iwa yi ko dara

Jọwọ gbami ni aiye ninu iwe rẹ Irohin-imọlẹ akọmọlede ti gbogbo enia ma nka ni ojojumọ ba gbolo awọn ọmọ Nigeria tio wa ni ilu Oyinbo sọrọ lori iṣẹlẹ buruku tio ṣe laipẹyi nigbati Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria. ibẹwo ilu Oyinbo ribitı awọn tise ṣe ipade kan nibẹ.

The best watch in its class




AJIBỌLA & SON
279, L. E D B. Shops,
Imman Ligali Street,
Ita Akani Aree,
LAGOS.

BI O BA NI

# Iwe—Titẹ

FUN

Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi Iwe itufọ tabi ijade Oku

ATI

Iwe Igbeyawo

KỌWE SI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸ IWE

**Modupẹ Printing Press**
16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

EKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌỌKU NI A SI NGBA

IRỌHIN KO TOAFOJUBA
Dan wa wo lẹkan soso ṣoṣo ko si ri iyatọ

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIK



ALE-BI-ELE Egbogi Tọniki Jamọnu titun ti gbogbo a a Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ gbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin g ogbo'

Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala lala ṣiṣẹṣẹ ti o kọ ie jẹun daradara, tabi ki o male sun da-da ọkun lọsan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbo-gbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala ṣiṣe tabi fun awọn ailera gbogbo 'nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN' ni egbogi ti e nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata anu rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bi ẹ s'i do dada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba y'Arẹ" ngbakugba yio salọ pẹlu igooaba-dun ati alafi diro de ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Ṣọbu: awọn

NIGERIAN- MEDICINE STORE
4, Tinubu Square Lagos

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos.
hone: 22878 Nigeria. (Ọja Ita Faji)
ATI NI AWỌN ṢỌBU
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY
IBADAN

# Ẹ O Leke Ajipete

Lati Ọwọ LHADJI Y. A. DISU

Ẹ maṣe fi eti si ọrọ asinwin, Ẹ maṣe fi eti si ọrọ kẹn'mani Ẹ maṣe fi eti si ọrọ onisọkusọ aronika Ẹ maṣe fi eti si ọrọ onisọndi sọndi Ẹ maṣe fi eti si ọrọ awọn ẹlẹgan Bi ọmọ enia ba ronu jinlẹ yio gba wipe iruiẹ awọn enia bẹ ẹ ti wa lati ọjọ ti alaiye ti da aiye.

Irufẹ wọn ni nwọn sọpọnpa gbe ogun ti Anabi Muhanmed, ki ikẹ ati ọla ma a ba a titi lai ai, tobẹ gẹ ẹ ti nwọn fi lẹ e jade ni ilu baba rẹ Mẹkka.

Nipa adura si Ọlọrun ati nipa ṣiṣe daada, Ọlọrun Ọba Ogo si da aabo bo o, ko si fun wọn ni agbara lati sọ ọ di akinrindin. ko si fun wọn ni agbara lati lu u fi a Ọlọrun ma a nṣe atilẹhin fun olododo ẹru rẹ ai, ki i si si lẹhin alabosi Ki i si gbe ẹbi fun alare Ki i si gbe are fun ẹ ẹbi.

Gbogbo ẹniti ibi rẹ ko ba pe perepere, ki o pe daadan bi Anabi, ọrẹ mi, (ki ike ati ọla ma a ba a titi lailai) tabi ti laakaye rẹ ko pe. ti laakaye rẹ so rikodo t bi ti o ba burẹwa ni o ma a nsaba ba ọmọlakeji rẹ jẹ kaakiri adugbo ati kaakiri ilu.

Doogo kẹnimani enia tabi enia kikuru bibsi ti ko ba ri iṣẹ kan ṣe tun fẹran lati ma a bi enia ti o ba san ju u lọ, ti iyẹn ko ba fun uu ni okele. Ẹni okele ri awọn ọlẹ, alapa maṣiṣẹ Onjibiti ni wọn jẹ.

Bi Alhaji Ọmọ-Oba Abudu Whaid Elias ti jẹ Ọlọrọ to lode toni ati ti Oloye Ọmọ-Ọba Aminu Kosọko ti ẹ Ọlọrọ to lode toni, ẹ ko jẹri wọn ki nwọn ma a ṣe ẹrẹkẹ eebu.

Nwọn bi wọn re. Nwọn si tun ara wọn bi. Nwọn ki iṣe ole enia. Nwọn ki si ṣe eburẹwa. Bi kẹnimani ati ọlẹ enia ba di ọtẹ, ti o si nra eebi si nyin lara ni o ta ọ. Ẹ dupẹ fun Ọlọrun, ki ẹ ma a gbara ni igbogbo igba Ki ẹ si ni igbagbọ si Edunmare pe, o otọ ni yio leke. Anabi Muhanmed leke awọn ajipete.

Anabi Yisa (Jesu) si leke wọn.

# YE IRAWỌ RE WO

AQURAIUS (Jan. 21-Feb 19) Oju ire ati Oju iyi ni gbogbo enia fi nwo ọ, o dara, o si tọ ki a ma ri ọrọ rere gbọ lẹnu rẹ.

PISCES (Feb 20-Mar 20) Ọjọ oni lo dara ki iyawo rẹ lọ ra ọja onjẹ tabi awọn nkan miran lati ọja wa sile, ṣanu fun ọrẹ rẹ kan ti o fẹ lati ya owo lọwọ rẹ ran a lọwọ,

ARIES (Mar 21-April 20) Ipade aladun kan mbẹ fun ọ loni iṣẹ rẹ yio si ma lo daradara,

TAURIUS (April 21-May 22) Ida wo kan ti o fẹ ṣe pẹlu ọrẹ rẹ kan yio yọri si rere pe kan ti nwọn o si pe ọ ni asalẹ oni yio mu ire daniju bi o ti ro lọ.

GEMINI May 23-June 21) Er owo kan ti o je, yio pẹ ki o to ri owo na gba eyi le fa enia si iranti ede koyede kan ri a ti ba ara ani ṣe lọjọ pipẹ sẹhin wa.

CANCER (June 22-July 22) Ṣọra nipa bi o ti ṣe nna owo, fi ẹsẹ rẹ le oju ọna ti o tọ, nipa inawo maṣe jẹ ọmọ on nakuna.

LEO (July 23-Aug 22) Ko nṣe ohun ti o ṣoro bi ọlọmu ba da ọmu iya rẹ gbe, ṣugbọn ajọṣe nyin li alẹ oni yio mu ayọ faaji dani.

VIRGO (Aug 23- Sept 22) Bi ọrọ ba di ọrọ owo nina, nṣe ni ki o yara ju ara silẹ Bi o ba si gba imọran ti ẹlomiran ọ ti rẹ yio ṣe iranlọwọ fun ọ jọjọ,

LIBRA (Sept 23-Oct 23) Gbogbo eto daradara ti o ti ṣe silẹ nipa iṣẹ rẹ fẹ daru, Ki o mura lati yi goo gbo rẹ pada.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Ko si ijọngbọn kan loju ọna, nṣe ni ki o rin tọ awọn ẹgbe rẹ lọ

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 21) Ohun kohun ti o ba de, maṣe mọ ọ ṣi ohun kan ẹnikan wa ti o nfi ojire wọọ ni gbakugba.

CAPRICORN (Dec 22-Jan 20) O le ṣe awọn atunṣe ti o ti wa lọkan rẹ lati ṣe ti o si mọlara koko yala sọdọ iyawo rẹ tabi ọrẹ rẹ, sa ṣe atunṣe.




## PORAL

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ẹ lẹnu on akan bi dun kan tabi jubẹ lo awọn egbogi rọ irọbi fun le se iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ se owo ofo mọ.

Bere fun egbogi awọn ara, ilu Faranse ti wọn npe n PORAL ojulowo hanunhanun, a amatase egbogi fun Iko otutu, Ikọ ọna ọfun, Ikọ Igbaaya, Ikọ iil , Ikọ ti o m mu enia tu kẹ ẹbẹ nigbakugba lati inu "Ifun wa (Lungs tabi ti o ba nmu enia ru pẹlu.

Bi o ba ra Igo kan PORAL yi wa Iwọ na yio ri iya tọ ninu ara rẹ ni kiakia Igbaaya tabi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro "IKỌ" rẹ yio si san ni patapata iwọ yio ma jeun daradara iwọ yio si un fọnfọn pẹlu alafia de.

Bere egbogi yi ni awọn orisiri i Ebo gi Ikọ miran ni Ṣọbu awọn:—

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square, Lagos
WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọjaita Faji) .... ....
Adedun Chemist
14, Weakman Street, Yaba

## MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING
*Firms Patroise* MODUPE PRESS
*Becuase Of Their;—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHOD
PRINTING

*For Your Next Printing Jobs —*
Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe
We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupẹ Printing Press**

**16 Bamgbose Street**
Phone 21985, Lagos

# Ẹsun Kekeke Tabi Iwa Nkan Si Lẹsẹ Nigbakugba To Wa Larin Wa

**Lati Ọwọ S. O, Jaiye**

Larin wa loni yi awọn ohun kan pataki to wa larin wa bi orilẹ ede ni awọn ẹsun kekeke tabl iwa nkan si ara ẹni lẹsẹ jẹ ohun pataki kan ti o nba arin wa jẹ. Arun kekere yi wọpọ larin awọn obinrin ati awọn kan to wa ti nwọn ko duro fun igbẹkẹle kan.

Bi iru iwa yi ti ṣe wa larin obinrin bẹni o wa larin awọn ọdọ. Iru iwa ti mo fẹ fi ọwọ ba yi jẹ ohun to le ba ile ati ona jẹ larin ọkọ ati aiya. O si le ko ipaya ba ọkunrin pupọ ti aiya rẹ ba ni iwa abọde yi. Ko si bi ọkunrin ti le ni agbara to ti iyawo rẹ ba ni iwa yi ti ko ni pin lẹmi.

Bi ọkọ ba pẹ ni ẹnu isẹ papa obinrin to ni iru iwa yi yo ko iyọnu lọ ba wipe on fun ra sii wipe on nikan ti o nwa lẹnu isẹ na. Tabi ti o ba jaja wa ri bale tabi ọkọ rẹ pẹlu obinrin miran agaga ija nla yo bẹ silẹ ninu ile ko tilẹ ni wadi ohun kan ki o to bẹrẹ si ba ọkọ rẹ ja wipe daju daju ẹni buburu ni ọkọ on ko kọ lati ro ẹjọ rẹ fun oṣo ati ajẹ tio ba ṣ ṣẹ funu.

Bi a ba sọkun a ma riran ohun to mu mi da ọrọ yi silẹ ninu iwe yi ni awọn ẹsun nla ati kekeke to nta gbongbo nilha Ila Orun lo ni yi.

Ko si ohun to wa larin Oloye Awolọwọ ati Akintọla loni ti ko si iru rẹ ri ninu aiye ti awa yi bi igba ti o koja ati igba ti ao tun ma lo.

Ki a ma tan ara wa, ija ti o wa larin Awolọwọ ati Akintọla ṣe pari ti o bi jẹ pe awọn ti nye si ọrọ ọlọrọ ba fa' ọwọ wọn ninu awọn ọrọ ahesọ ti o wa nilẹ.

Ni ibẹrẹ ilosiwaju ati idasilẹ Ẹgbẹ Afẹnijẹre ko si si eyi to ṣe ẹhin awọn mejeji yi bakanna bi ro ẹbodiyan ti ṣe wa silẹ ko si eyiti awọn mejeji ko mọ.

Bi ọrọ ba si ri bayi ko si atunṣe ti awọn mejeji ko le pari. Lẹhin ipari ija yi ko si agbara ti o tun le kọju ija si wọn mọ. Nitori nwọn ti koja larin ofi ati ọọla aiye. Iru eyi ni awọn agba wa npe ni i inlẹ iriri aiye.

Nitotọ tia ba rono wahala ti o wa ninu gbogbo nkan to wa nilẹ a ko ni i ba ẹnikan ṣe pọ mọ lailai.



Ọgbẹni S. O. Jaiye

Ninu iwahala kikun ni enia ndi alagbara ati irunmọlẹ aiye.

Gbogbo awọn orisa ti a nsin ni ilẹ wa lo ni jẹ enia kan ni igba kan ri. Ṣugbọn lẹhin iwahala ati inira gbogbo nwọn di ẹniti awa nsin ti a si npe nwọn ni ẹni ailegbagbe.

Ki a ma tan ara wa jẹ ọrẹ npa ọre, ọmọ npa baba rẹ bi baba ti npa ọmọ rẹ ni aya npa ọkọ ti ọkọ papa npa aiya rẹ fun iwa aidọgba larin nwọn.

Ki a ma sọ ti awọn amọ ofin ti awọn ti awọn na tun nda lẹ ara nwọn. Ti ilẹ wa yio ba dara a ni lati ri iru gbogbo nkan ti o nṣẹlẹ loni yi.

Ni temi ninu aimọkan mi mo ro wipe onilaja ododo ni ko si larin awọn ẹni pataki meji yi ti ina ikorira ko ṣe parun mọ Ko si ohun ti ko ṣe pari larin wọn to wa ni ilẹ yi.

Ẹma jẹ ki agbagbọ pe ọrọ Akintọla ati Awolọwọ ko le tan titi aiye ọrọ ibajẹ ni iru ero bẹ.

Ti o ba si ri bẹ mo ro wipe ati pe iru awọn aṣaju bẹ ni irunmọlẹ tabi ẹni ti o yẹ fun iranti titi aiye yo jẹ ohun iṣoro pupọ.

Daju bi nwọn ba ja ju bẹ lọ. Gẹgẹ bi ẹda ti o ni igba diẹ lode aiye ani lati ranti nkan nwọnyi ki a ronupiwada kuro ninu iwa arankan.

Ọrọ Ọlọrun sọ wipe, "Iwọ wipe iwọ yo ma ṣe iyalode titi o ko si ro igbẹhin rẹ o ko si fi nkan wọnyi si ọkan rẹ. Kini igbẹhin ẹda? Mo ro wipe iṣẹ ti enia ba ṣe silẹ fun ohun iranti si rere ni ohun to darajulọ

Ki enia to di irunmọlẹ tabi ẹni iranti oluwa rẹ ni lati jẹ piri iya fun ẹda si ẹlẹgbẹ rẹ. Bi ẹṣẹ kekere ba wa lọwọ enia ti ko ba si ju silẹ ọjọ ibẹwo ba de oluwa rẹ yio kabamọ.

Nitori na wipe igbẹsan ni a o ma wa larin ara ẹni si ara ẹni. Yẹyẹnatu ni gbo rẹ yio jẹ Oluwa nikan lo ni ẹsan lọwọ nitori na Ọlorun sọ pe Ọlorun ẹsan li On

Nitori na mo bere wipe eṣe ti awa ko jọwọ ẹsan fun Ọlọrun Ko si ẹda ti ole gbẹsan fun ara rẹ

Ti eyi ko ba daju jẹ ki a dan wo Iwọ yo ri pẹ otọ leyi Bi iwọ ko tilẹ gbe mẹta lai sun Bẹni iwọ ko gbẹsan fun ara rẹ

O tilẹ jẹ ohun iyanu fun mi pe awọn oṣelu wa bẹrẹ si le ara nwọn kiri bi ẹnipe a nle ole larin ọgan ọ oru' E yi nkọ iru iwa bayi ko dara rara Ti aba tilẹ le ara wa pa tan kini adun to wa laiye ara ẹni mo tilẹ ro titi pe ko si enia to g bi awa ti anpe ara wa ni enia

Mo ro pe ki ab ara wa se ọpẹ alaye ni adun Aiye wa Bi a ko ba ara wa se asọye ati apero ni bo ni adun aye wa

Mo ni ro wipe ti ẹda ko ba ba ara nwọn ja ki nwọn si pari ọrọ larin wọn adun ko si gẹgẹ bi ti ebi ko ba pa enia onjẹ kini adun dada

Nitori na ẹnyin ara Iwọ Orun Ile abinibi wa di ọwọ nyin odi ọwọ baba Ọrun.

---

Lati Oju Ewe Kẹrin

alafia ilu fun apapọ Ijọba Naijiria Alhaji Shewu Shagari se ileri fun Alakoṣo ẹlẹgbẹ rẹ pe on yio siri da ju pe gbogbo ọrọ ẹdun ọkan Ijọba Agbede meji ipinlẹ Iwọ Naijiria to mu wa siwaju on pe Ijọba apapọ ilẹ Naijiria yio tete ṣe iranlọwọ eyi ti tọ ati eyi to yẹ fun Ijọba ipinlẹ na laipẹ.

Ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi ni awọn Alakoṣo eto alafia ilu mejeji na si bẹrẹ si ṣe abẹwo si awọn ile isẹ Panapana ti ilu Eko ati agbegbe rẹ lati le wo gẹgẹbi isẹ awọn panapana ni awọn ile isẹ na.



# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 761. WEDNESDAY, AUGUST 5 1964 (2D)

## Awon Olopa Ti Okunrin Kan To Kegbe Awo Mole

IBADAN:- Ni ojo Isegun ti ise keji osu yi ni awon Olopa mu Okunrin kan ni bi eye ikomo jade kan ni adugbo Opopoiyemoja fun esun pe o nkegbe Awo ni bi eye ikomo jade na.

Irohin tun fi ye wa pe okan ninu awon Alakoso kekere ti Ijoba ipinle Iwo Orun Naijiria ati Olori egbe N. N. D P. si wa nibi eye ikomo jade na nigbati omo kunrin na si nkegbe Awo ieseke se na ni nwon ti ranse si ibudo awon Olopa ti Ijoba Ibile ipinle Iwo Orun to wa ni Gege, Ibadan lati wa mu okunrin lo si itimole fun esun pe o nkegbe Awo

Ni ojo keji ti awon Olopa lo ti omo kunrin na mole ni nwon mu lo siwaju adajo ni ile ejo ibile ti Oke-Are. Awon Olopa si fi esun pe omo kunrin na Lademeji Ladeji pe o ba enia ja lona ti ko to.

Sugbon nigbati adajo ile ejo na bere lowo Ladeji pe o jebi tabi ko jebi ni o ba da dojo l'ohun pe on ko jebi rara Oniwe irohin wa fi ye wa pe ojo keji la osu yi ni won fi ejo na si lati ma ba lo ile ejo na si gba iduro omo kunrin na,

## Awon Egbe Akeko Afenifere So Pe:

# LAISI AWOLOWO, KO LE SI OWO NILU

IBADAN:— Awon egbe akeko ti egbe Afenifere so ni nu ipade won ti nwon se ni ilu Ibadan lapa pe vi pe laije pe Oloye Obafemi Awolowo jade kuro l'ogba ewon ati lati le wa se eto akoso ati gegebi alafia ati Ijoba rere pelu gegebi eto isuna yio se ma lo gere pe ko le si owo kankan mo ni Orile-ede Naijiria.

Awon oro wonyi njade nibi ipari eto ipade ti awon egbe akeko na fi ojo meta se ni ilu Ibadan eyiti o wa si opin ni ojo Aje ti ise ijo osu yi ni Ogbeni Kayode Adewale ti so pe laije pe Oloye Awolowo tabi egbe Afenifere wa pe ko le si eto Ijoba alafia lai je pe egbe Afenifere lo nse akoso Ijoba ile Naijiria pe ko le si eto ofin rere ni ile Naijiria patapata.

Ogbeni Adewale ti o je Alaga agba Akeko ti Afenifere na tun fi iye awon omo egbe re pe ogba ewon ti Oloye Awolowo ati awon omo ehin re wa pe ko fa chun rere wa si Orile jakejado ile Naijiria

Alaga egbe awon Akuko se apejuwe olori egbe Demo NNDP pe oje eni kan to feran lati ma soro pupo



Oloye AWOLOWO

sugbon eru si nba lati le lo ro ati pe owo be dabi eni dojuko awon eniti yi dibo pe nse ni nwon na owo na lati leri eniti toto ati eyiti o ni ina kuna.

ye lati se Akoso won Alaga egbe na tun se alaye pe chun ti to ati eyito si ye fun egbe Demo NEDP na yi nipe ki o mura lati tu ile igbimo Asofin Ipinle Iwo Orun ka lati lemo gege bi e ia na se feran egbe on si

Alaga egbe Akeko na tun bu enu ete lu Ijoba ti egbe Demo tun nse akoso re lo ri awon Alakoso Ijoba ti awon egbe naso pe oti poju atipe ki nwon ge owo osu awon Alakoso na kuro die ati ona oya ti Ijoba Ipinle Orun Eyiti Egbe Demo nse akoso nsan fun awon Alakoso na.

Ogbeni Kayode Adewale tun so pe nse lo ye nisisi yi lati lo fi op n si awon owo ey ti Ijoba pinle Iwo orun Naijiria na san fun awon oga ni ile ise ayiri Ijoba ipinle Iwo orun nse akoso pe ki nwon da iru owo te du-

Ogbeni Adewale tun se alaye pe nibi ti awon osise ni Ipinle Iwo Orun Naijiria ti ngba Adota Ponun (£50) l'odun kan pe ibe na ni Minista kan ti ngba Egbedogbon ponun (£5000 l'odun kan na.

Awon egbe Akeko ti egbe Afenifere tun so ninu ipade won pe awon ko ni ero pe ile Naijiria padanu ninu ipade isokan fun ile Afrika eyiti nwon sese so ni ilu Cairo laipe yi (OAU) ati pe ki ise pe ile Naijiria padanu rara nipa fifi ile ipade na si Adis-Ababa,

Awon egbe Akeko egbe Afenifere na tun se alaye ohun to fa ti ile Naijiria ti padanu lati gbe ile ipade na bi ile Naijiria ni pe alaibikita fun awon ilu Okere miran o si fa ti ile Naijiria si padanu.

## Okoti-Eboh Lo Ba Sardauna Soro Asiri

LATI OJU EWE KINI

Koju bi nkan bi iseju marun ti oko ofurufu ti o gbe Alhaji Ahmadu Bello lo kuro ni ibudo oko ofurufu na ni Oloye Festus Okotie Eboh lo sibi oko ofurufu to gbe wa si Kaduna ti o si ki gbogbo awon Alakoso ati awon egbe Olomi to ba won se ipade pe o digba die. Sugbon nigbati Oloye Festus Okotie-Eboh fe ki Alakoso eto isuna ti Ipinle Ariwa Alhaji Aliyu ni Oloye Okotie-Eboh ba si fila "Awo" to de lori ti o si tun ki Alhaji Aliyu pe "E se pupo" (Thank you sir")

Nigbati Oniwe Irohin wa fe ba Oloye Okotie Eboh soro nse ni Oloye Okotie Eboh yarawo inu oko ofurufu lowo wa si ile Kaduna

Lehin nani Oniwe Irohin tun sope on gbo pe lati Bauch ni ipinle Ariwa ni Okotie Eboh ti wasi Kaduna atipe Yola ni otun gbalo

Irohin tun fiye wa ninu awon enia to wa ki Oloye Okotie Eboh pe odigba die ni Alaga igbimo eto idibo Ogbeni E. E. Esha.

## Awon Afogota Ri Oku Omo Kekere Kan Ninu Gota

EKO:— Ni deede agogo kan osan ana ti ise ojo kerin osu kejo Odun yi ni ese aimoye enia ti o nkoja ni opopo Bamgbose nya si owo osi ati otun won lati wo oku omode binrin kekere jojolo ti awon afogota ri gbe ninu gota nigbati nwon nfo gota ti o ti kun ni egbe ile Egbe Awo [LODGE] ti o doju ko ile ise Iwe Irohin Imole ni Bamgbose

Omode na ti ni ori, imu, oju, owo ati ese, sugbon ko ju omo oyin osu meta si marun lo o si je obinrin, o ti ni irun die lo.

Awon Olopa lo wa gbe oku Omode kekere na, a lero pe nwon yio ni sin oku omo na lana.

Printed and Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street Lagos 5/8/64.